# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 704 TUESDAY, MAY 26, 1964 (2D)

## Ẹniti Nwa Ifa, Nwa Ofo

IBADAN, Ọgbẹni O. Ọdunlami, adajọ Agba ile ẹjọ kekere Ibadan ṣe idajọ pe ki awọn ọdaran mẹta kan, Bello Ṣoketo ẹni ọdun mẹtadinlọgbọn, Bako Kano, ẹni ọgbọn ọdun ati Liruanu Danwanom ẹni ọdun mejidinlogun si ẹwọn ọdun mẹta nitoripe, nwọn jẹbi ẹsun jibiti ti awọn Ọlọpa mu wa si ile ẹjọ ni ọjọ Ọjọ'Bọ ti iṣe kọkanlelogun oṣu yi.

Ọlọpa ti o ba awọn ọdaran mẹtẹta ṣẹjọ ṣe alaye pe, awọn ọdaran na lọ si arin ọja Saho ni ọjọ kẹrindinlogun oṣu keji ọdun yi, nwọn si nṣe "Eyi-jẹ, Eyi-o-jẹ".

Ṣugbọn nigbati nwọn ri ọkunrin ti o wa si ọdọ wọn, ti nwọn si ṣe akiyesi pe, owo wa lọwọ rẹ ni nwọn ba sọ fun ọkunrin kan, John Wosa, pe ki o mu pọnun meji pere (£2) wa, awọn yio sọ di ọdunrun pọnun (300) fun John.

Lẹsẹkẹsẹ ni John ba yọ pọnun meji jade ninu apo rẹ, o si ko owo na le wọn lọwọ ṣugbọn o duro lati ọsan titi di alẹ pọnun meji ko yipada, awọn ọdaran na si kọ lati fun u ni ọdunrun pọnun tabi pọnun meji rẹ ti nwọn gba ni ọgbẹni John ba lọ fi ọran na han awọn ọlọpa ni tesan, nwọn si mu awọn ọdaran na.

Lẹhinti adajọ ti gbọ ẹjọ na tan ni o ba ṣe idajọ pe, ki Bello Sokoto lọ si ẹwọn ọdun meji, Bako ati Danwanom lọ si oṣu mẹfa, mẹfa, nitoripe awọn lo ṣe iranlọwọ lati gba owo na fun Bello Sokoto-Onijibiti.

## Iwadi Ekunwo—Oṣu Awọn Oṣiṣẹ O Jade Loni

# IJỌBA FẸ SAN OWO GỌBỌI FUN AWỌN OṢIṢẸ

EKO:— Ni deede agogo meji Ọṣan ana ni irohin kan wa lati ile iṣẹ Minista alamojuto eto irohin fun Apapọ Ijọba Najiria, bọya irohin iwadi ẹkunwo Oṣu ti Apapọ Ijọba yan lati wadi ẹkunwo Oṣu fun gbogbo awọn Oṣiṣẹ jakejado Orilẹ-ede yi.

Irohin na tun ṣe alaye pe ile iṣẹ itẹwe Minista na ti oṣiṣẹ tọsan toru lati ma a tẹ iwe abayọri eto iwadi ẹkunwo na

Irohin kan lati ile iṣẹ itẹwe na fi ye wa pe, awọ dudu ni pali ti o wa lẹhin iwe iwadi na, ṣile marun (5/-) pere ni Apapọ Ijọba yio ma a ta iwe na.

A gbọ wipe ọkẹaimọye enia jakejado orilẹ-ede Naijiria ni nwọn ti fi owo ranṣe lati ra iwe iwadi ẹkunwo na.

Gẹgẹbi irohin ti o tẹ wa lọwọ ni ọsan ana, agbọ wipe Minista Alamojuto eto idasilẹ iṣẹ, Ọgbẹni J. C Ọbande yio ba gbogbo awọn Aṣiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ sọrọ ninu ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ni deede agogo mẹwa owurọ yi.

Ọrọ ti Minista na yio ba wọn sọ jẹmọ abajade iwadi Igbimọ Morgan ti Ijọba fẹ gbe jade.

Ijọba fẹ ba awọn Asiwaju ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ na sọrọ lori abajade Igbimọ Iwadi na ki nwọn to tẹ jade fun gbogbo aiye lati gbọ.



Oloye J. M Johnson
Minisita Alamojuto Eto Iṣẹ

Bi ohunkohun ba si fẹ atunṣe ninu iwadi na eyiti o le mu awọn oṣiṣẹ binu, a gbọ pe, iru nkan bẹ ni awọn enia na yio jiroro le lori pẹlu Minista na loni ninu Ile Igbimọ.

Lẹhinti awọn enia na ba fikunlukun, ti awọn ẹgbẹ mejeji (Ijọba ati oṣiṣẹ) ba gba iwadi na, nigbana ni nwọn yio to tẹ jade.

Bi ko ba si ija tabi ede-aiyede larin awọn mejeji ninu ipade ti nwọn fẹ se ni owurọ yi a jẹ wipe, Ijọba yio kede iwe na, nwọn o si gbe irohin na jade.

Bi o ba jẹ be, a jẹ wipe, gbogbo ohunti Ijọba ba wi, ati iye owo ti Ijọba yio ba fi kun owo oṣu awọn oṣiṣẹ, yio jade ninu iwe irohin wa ni owurọ ọla fun gbogbo ẹnyin onkawe wa.

Oniwe irohin wa Ejongboro yio lọ si ibi ipade na ti Ijọba fẹ ba awọn asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ ṣe ni owurọ yi.

Ṣugbọn oniwe irọhin kan ti o nfi imu finlẹ kakiri ile iṣẹ awọn Minista Alamojuto eto iṣẹ fi ye wa ni ana pe, Ijọba fẹ fun awọn oṣiṣẹ ni ẹkunwo owo oṣu gọbọi, eyi ti yio to enia kọọkan na ki oṣu to pari.

O tun fi ye wa pe, awọn ti owo oṣu wọn kere ni Igbimọ iwadi Morgan sọ pe ki nwọn ma a san owo oṣu gọbọi fun.

Ṣugbọn owo pọọku-pọọku ni Igbimọ na sọ pe ki nwọn fi kun owo oṣu awọn ti ngba owo gọbọi tẹlẹ.

Gẹgẹbi ero ọkan oniwe irohin wa, o ni on ro pe, Igbimọ na fẹ ki owo oṣu awọn Ọga ati ọmọ iṣẹ ki o maṣe jinna pupọ si ara wọn nitoripe ọja ti iyawo Ọga ti nra ọja, ọja kanna ni iyawo awọn lebira ti nra ọja.

Iye ti nwọn si nta nkan fun awọn iyawo ọga na ni nwọn nta fun awọn iyawo lebira. Ṣugbọn oniwe irohin wa na ko le sọ pato fun wa iye ti nwọn fi kun owo oṣu oṣiṣẹ kọọkan, ṣugbọn ti irohin na ba ti jade ni owurọ yi ẹ o gbọ gbogbo rẹ ninu iwe irohin wa ni owurọ ọla.



Ọgbẹni J. C. Ọbande

Oniwe irohin wa kan ti o lọ ba Alhaji Adebọla ni alẹ ana fi ye wa pe, ni ọjọ kọkanla Oṣu yi ni Ọgbẹni J. C. Ọbande Minista Alamojuto eto idasilẹ fun Apapọ Ijọba Naijiria ti ṣe ileri pe ni ọsẹ meji si i, ni Ijọba yio to gbe eto abayọri ẹkunwo na jade.

WO OJU EWE KẸFA



Ọgbẹni Michael Imodu



Ọgbẹni L. L. Boral



Whabi Goodluck

# ITAN AJIRAN ILU AWỌN OKU ( Apa 9 )

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Nihin ni ndifa ti sii loju ala pe, ogun yio ko ilu wọn. Ẹma kaa nṣo mo si ntọrọ idariji fun ọrọ aibikita ti o sọ si Ọkọ rẹ. Mo fẹ ki ẹranti pe ad·fa ti ri loju ọpọn ifa rẹ pe ogun yio ko Ọba ati awọn ilu rẹ ni igbekun, ayafi ti Ọba ba le jẹki Ogboju-le Ogun fẹ Ọmọ rẹ, eyi lo le gba' wọn la, jiji ti nwọn ma a ji larọ kutu-kutu, igbe "ẹgba wao, Ogun de o"!! ati irọkẹkẹ Ogun ni nwọn ngbọ.



AWORAN OKE YI NI TI AJIRAN ILU AWỌN OKU

Ọba, ẹmẹwa, ayaba, ilu ati awọn ẹgbọn Ogboju-le-Ogun ti daa mu. Nwọn nsa sihin, sa sọhun.

Iyawo Ogboju-le-Ogun pee oni Ogboju-le-Ogun Oni o d'ọwọ rẹ, o dabun oni o d'ọwọ Ọlọrun gẹgẹ bi ẹnyin paapa ti mọ̀ipe bi Ọkunrin lẹ ju "Iso idi lọ" oni lati fọnnu loju iyawo rẹ.

Ogboju-le-ogun bẹrẹ si jẹ atare, o npọfọ ki ogun le rọ ri, ṣugbọn nwọn tubọ nsumọ bode

Ko mọ ohun ti yio se mọ ọkan rẹ poruru on wo su u bi ẹniti nwọn ṣepe fun Ogboju-le-ogun ko ni ọrẹ alaye ri a fi ẹbọra ẹniti o si jẹ ọrẹ rẹ korikosun ni Eṣu ọdara nwọn timba ọrẹ wọn bọ ọjọ ti pẹ, nitoripe nigbati Ogboju le-ogun ti wa lọdọ arọni ni nwọn ti mọ ara wọn.

Eṣu ni ẹniti o se igbakeji ọkọ iyawo ni ọjọ ti Ogboju le-ogun fẹ ọmọ Ọba ẹnikẹni ko mọọ nitoripe o gbe agọ enia wọ Iye Ogboju-le ogun sọ o ranti pe Eṣu wa lọdọ on atipe nkan bi ogun bi ọtẹ bilisi eṣu lo ndaa silẹ ọrọ lọkan ara rẹpe ti on ba ran eṣu si ogun ti o mbọ yi yio da wọn ru

Lọgan ọrẹ eṣu oni iwọ ọrẹ mi atata ati jo se ọjọ ti pẹ ko si iṣẹ ti Ole ran mi ti nko ni lọ. Okun le loni Aganyin ko le wẹ Ti ogun ba ko ilu yi mo dẹni ẹsin, mo dẹni Iya, mo dẹni a fi dapare, mo dẹni iyọṣuti si, nitoripe emi ni awọn ara ilu gbẹkẹle pe ngo gba wọn silẹ.

O dọwọ rẹ loni o, iwọ ọrẹ mi eṣu! Ba mi ko sarin ogun ti o mbọ yi, ki o da imọ wọn ru. Kọmọ ogun maṣe gbọ ti Balogun, konifere fi gbigbọ se alaigbọ.

"Iwọ Eṣu lalu okiri oni ṣokoto penpe ti ngṣni-bode Ọlọrun ọba ẹlẹkun sunkun, k'eru ba ẹlẹkun.

Ẹlẹkun nsunkun, alaroye nsun ẹjẹ. O de. ki ile onile to. Onilọ niru ẹpa anri ipa-rẹ firi-firi ọpẹlọpẹ giga to ga, nigbati Eṣu gbọ oriki rẹ, ori rẹ wale

O y rapada, obọ agọ enia silẹ odi eṣu o di bo o lọ, o ya fun mi, eṣu bẹ sarin awọn ogun to mbọ o da wọn lede ru.



Ọgbẹni J. O. SHOYINKA

Gẹgẹ bi ẹnyin na ti mọ pe Balogun ni olori ogun, aṣe ti o ba pa, ko si ẹniti o gbọdọ kọ pe on ko se bẹ ẹ Ẹnikẹni ti ko ba si se bẹ ẹ o di pipa ṣugbọn nigbati eṣu tẹ si arin wọn o le ẹmi Ọlọrun jade lọkan wọn o wa jọba ninu wọn.

Balogun paṣẹ fun onifere pe ki o saju ogun o kọ jalẹ inu bi igbakeji Balogun, o fu ida rẹ yọ o bẹ oni-fere lori. Awọn ọmọ ogun fẹran oni-fere yi pupọ toripe o mọ fere ati orin iwuri fọn tobẹ gẹẹ to jẹ pe ko si ogun ti nwọn le lọ nwọn kii nsẹgun nitoripe ti nwọn ba ngbọ fere rẹ ori wọn a ma a yi nwọn asi ma ja laibikita bi akura eyi mu ki awọn ọmọ ogun pori biri, kolo nwọn ko nkan ija silẹ nwọn si ran ori jalẹ pe awọn ko ja mọ idaji ninu wọn ran ri, idaji gba lati ja.

Nwọn fi ija pẹẹta nigbati eṣu bẹ sarin wọn, nwọn bẹrẹ si ba ara wọn ja nwọn ja titi ti nwọn fi pa ara wọn tan nigbati Balogun ati igbakeji rẹ ri ohun ti o sẹlẹ nwọn tọwọ bọ inu apo wọn, nwọn si bu majele (poison) jẹ bẹni eṣu ṣegun fun Ogboju-le-ogun.

Inu Ọba ati awọn ara ilu dun wọn fi Ogboju-le-ogun jẹ igbakeji Ọba ajọyọ ọjọ na ko se f'ẹnu sọ. Bayi ni ọrọ Baba-Iwo ṣe.

Irohi ko to afoju ba ni ọjọ ti Ogboju-le-ogun nṣe ikomọ rẹ, Ọtalenirinwo ọba lo wa si bi ikomọ awọn enia pọ to bẹẹ gẹẹ ti ako fi mọ enia yatọ si ẹbọra.

Orisirisi onjẹ aladun ni o wa nibẹ, ọti jinni npe bia ranse, ẹmu ko tilẹ raye duro rara, agbala Ọba gbojikan fun ilu. Nigbati ẹsẹ pe biba gbogbo enia pa lọlọ, Ọba pa laṣẹ pe ki Ogboju-le-ogun sọ ọmọ rẹ lorukọ, o pe ẹgbọn rẹ agba sẹhin, o bere orukọ ti on yio sọ ọmọ na ẹgbọn rẹ ni ki o sọ ọ ni "Ẹgbẹji" o si sọ bẹẹ.

Ọba, Ayaba, awọn ara ile Ọba, ati iya ọmọ ṣbẹrẹsi sọ ọmọ na lorukọ lorisirisi gẹgẹbi ẹnyin na ti mọ pe bi enia ba ti ni ẹbi si bẹni orukọ ọmọ na a fi pọ. Gẹgẹ bi ẹnyin paapa ti mọ, ni igba lailai, nwọn ki iṣe ki wọn ma kọ ila fun ọmọ wọn, nitoripe lasiko igbana ogun ọtẹ, ọmọ jiji gbe pọ.

Eyi jẹ idi pataki ti awọn ara igbani fi i ma a nkọ ọmọ wọn ni ila (tribal mark)

Ohun ti o mu ki Ige da imọran ila kikọ yi ni pe alejo ni awọn jẹ ati pe, ẹni ṣọrẹ ero le ma yọ, ero nre le rẹ bo dọla. Irin ajo ni awọn nlọ ki Eledumare to fi ọmọ yi jinki wọn nwọn ko si le fọwọ sọya pe nwọn o tun pada mọ, ṣugbọn ti awọn ba kọ ọmọ yi ni ila ti o ba di gende, ti o ba tilẹ jẹpe awọn ku si irin ajo wọn, yio fi ilu Ọba Onilogbo wẹ lọ, awọn ara ilu yio mọ pe ọmọ ọmọ onilogbo ni, awọn yio si gba tọwọ tẹsẹ.

Tani a le fi jọba ki o ma sọ ipakọ lukeluke ? Tani o jẹ gbadura pe ki on ti idẹra bọ si inu inira. Ogboju-le ogun ati awọn ẹgbọn rẹ ti yọ di bi ajanaku, paapa Ogboju le ogun, awọ rẹ ndan bi kolonjia irun ori rẹ dudu kirikiri aiya rẹ ṣẹpọn bi ti ẹlẹdẹ, apa ati ẹsẹ rẹ ri ribitiribiti bi ọmọri odo arẹ idi rẹ ri lanti, o nyi biribiri bi ti Wundie ti ko mọ ọkunrin, a fi aijẹ obinrin oloyun, ehin re funfun bi ẹgbọn owu

Arẹ de ba wọn, nwọn nbere lọwọ ara wọn pe Njẹ yio seese lati tun fi ara da wahala yi yi mọ ? Nwọn dakẹ ọkan, gbogbo wọn da ru, nitoripe nwọn mọ pe iya wa niwaju wọn.

Nibiyi ni ngo da ọrọ mi duro loni, ṣugbọn ki ẹ maṣe gbagbe pe, ngo tun ma ba itan na lọ ni ọla.

O darọ o.

# IWE SI OLOTU

## Ọyọ Nfẹ Atunṣe Ijọba

Olotu, inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye lati kesi awọn Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria lati le ba wa ṣe atunṣe ọpọlọpọ awọn oju ọna to wọ arin ilu Ọyọ, ọpọlọpọ awọn ọna wọn ni ọda ti nwọn da si ọna na ti kuro ti awọn Ijọba ko si ṣe atunṣe awọn oju ọna wọnyi.

Eleyi si mu ipalara wa fun awọn onimọto to nrin awọn oju ọna wọnyi papajulọ, awọn to ngun basikulu.

Inu wa yio dun bi Ijọba Ibilẹ Ọyọ ba le ṣe itọju awọn ọna wọnyi ati pe yio tun mu anfani wa si ilu Ọyọ fun awọn ọpọlopo ọja to yẹ ki o wọ ilu na yio ma ni aye la ti wọ arin ilu wa ra ọja.

Mo dupẹ o, Olotu.

Emi ni,
Anthony Ọrẹkọya.

ỌYỌ.

## Ẹla Eyi Ye mi

Inu mi yio dun pupọ bi olotu iwe Irohin Imọlẹ bale gba mi ni aye lati bere Ọrọ mi lọdọ awọn Ọjọgbọn ati Oloye yi nka iwe nyin nigba gbogbo.

Ọrọ mi na lọ bayi:- Awọn Ọmọde meji kan wa ti nwọn fẹran arawọn. nwọn ngbe papa, nwọn jijọ da owo jọ lati fi ra epo Oyinpo sinu apo ti nwọn jọ nlo.

Ọkan ninu wọn ra ẹrọ idana ti o njẹ Stofu o si ra epo ti ẹrọ idana lọtọ ṣugbọn ti o ba ti lo epo tirẹ, o tun nji epo ti nwọn jijọ ra lati ma fi tan na lo.

Owa di Ọjọ kan bi o ti fẹ ji epo yi bu ẹnikeji rẹ ba ri o ni ha! aṣe iwọ lo njẹ ki epo wa tete tan. Bi o ba to Sitofu lo, kini se ti o ma lo igi bi temi? kaka ki o bẹbẹ oni ki o ṣe ifẹ nu rẹ.

Ẹjọwọ kini ki ẹnikeji ṣe? ṣe ki nwọn ma jijọ ra epo pọ ma ni? koye mi.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi Ọlọrun yio bo asiri ami o.

Emi ni,
M. A. Aransiọ

OSHOGBO

## Ẹ gba Eyi Yẹwo

Ayọ nla ni yio jẹ fun mi ti ẹ ba le tẹ iwe mi yi jade ninu iwe Irohin oyin o'oyin momọ.

Mo fẹ ki awọn Minisita ti nwọn nṣe Alakoso Ijọba Apapọ Ilẹ Naijiria ma ṣe abẹwo yika ile wa,

Ọpọlọpọ enia ni ko mọ wọn soju, pẹlupẹlu awọn Minisita na ko tilẹ mọ ibiti ilu miran wa ju akajuwe ninu iwe ti nwọn r I lọ!

Ti nọọ ba le ma kakari nwọn na yio le mọ awọn ohun ti ile wa nfẹ fun ilọsiwaju

Mo dupẹ lọwọ rẹ, Olotu

Emi ni,
ỌLA LADELE

Igbẹti

## Jagun Jagun wọlu

Inu mi yio dun ṣẹṣẹ ti ẹba le bami tẹ iwe mi yi jade fun gbo awon on kawe Irohin yi ka

Iya lẹnu nla ni ọrọ yi jẹ fun gbogbo ọmọ Ijesha ni ọjọ aiku ti ise ọjo karun osu yi nigbati awọn olori Ẹgbẹ Demọ ko awọn janduku ẹgbẹ wọn de arin ilu ti wọn si bẹrẹ si luwa kii la i ja airoiẹlẹ

Ọrọ yi jẹ ijoju fun gbogbo enia ti o fẹ lọ gbọ ọrọ ti wọn fẹ wa ba wa sọ.

Bi o ba jẹ wipe awọn ẹgbẹ Demọ ti fẹ ṣe wa ni yi yio dara fun awa ọmọ Ijesha ti a ba iete jina si awọn ẹlẹgbẹ darudapọ yi

Mo dupe lẹwọ yin olotu mi ọwọn Ọwọ yin yio ma roke o.

Emi ni
James Ogedegbe

Ilesha

## A dupẹ o

A dupẹ pupọ lọwọ nyin ati awọn oṣiṣẹ to labẹ nyin fun iwe nyin oloyin momọ ti a tete nri ka ni Shomolu ati Bariga nigba gbogbo.

Inu wa si tun dun pupọ fun awọn itan oloyinmọmọ ti a nri ka ninu iwe na papa julọ awọn ọrọ lati ẹnu Yẹyẹnatu to fun wa ni ọgbọ .

Awa si mọ pe Irohin Imọlẹ si ti di araba. A tun dupẹ gidigidi ọwọ Olotu pẹlu Alakoso ile iṣẹ na fun alaye ti nwọn tun ṣe lori iwe oloyinmọmọ na pe ko fi ara mọ ẹgbẹ oṣelu kankan ati pe ọpọ lọpọ enia lo si nro pe ti ẹgbẹ UPP ni iwe na iṣe sugbọn gbogbo enia ni eyi si ti da loju pe ki iṣe bẹ rara. Ẹ ku iṣẹ, iwaju ni ọpa ẹbiti nyin maa resi o.

Emi ni
Joseph Ọrẹkọya

SHOMOLU

## Ero Mekka Ẹ kabọ

Nba dupẹ pupọ bi olotu bale gbami ni aye diẹ ninu iwe Irohin rẹ ti njade lojojumọ lati ki awọn ero Mekka ku abọ irin ajo mimọ ti wọn lọ ni alafia ni wọn de ni alafia pẹlu.

O jẹ ohun ayọ ati idunu fun mi ọpọlọpọ wipe ọpọ nina awọn ọmọ Najiria lo lọ si Mẹkka ninu

Ọdun yi, Awọn tolọ nile wa ni Ijọmu Oro awon bi Alhaji Mohummaed Adekanye mo koko ki awọn na pe wọn ku ori rẹ o Ọlọrun yio ma moju to wọn Awọn ti wọn si ku si Mekka Ọlọrun gba ẹsin wọn ki o si dari ẹsin wọn ji wọn Mo ki Musulumi Najiria pe wọn ku orire Ọlọrun alanu ko ni se ni ewo Musulumi to ku Amin

Emi ni,
Yesufu Oyinloye

FKO


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* *MODUPE PRESS*

*Because Of Their:—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs. —*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Services

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Steet,**
Phone 21985, Lagos.



# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBOGI



## "CYCLOVEN"

Aworan oke yi fi han gbangba ibiti Jedijẹdi rẹ gbe wa lara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigbagbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi Iho idi enia ibiti a ma ngbe ṣe igbọnsẹ. Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun Ọkuarin ti o si lagbara pupọ lati ṣe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri lode nisiyi ti wọn a ma po owo wọn fun iwosan rẹ ṣugbọn boya la leri mẹwa ninu ọgọrun ti o le ṣe iwosan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe bọya bi wọn ba lọ si ile Dokita lati lọ ke eyiti o ba nyọ jade lati omusu ku ni pa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Ṣugbọn awa ko ro be rara. Lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana. Orişirişi Jẹdijedi ni o wa ekini ti o bẹrẹ nipa aiko mẹ ṣe igbọnsẹ dede tabi lojojumọ, ẹlomiran nipa ijoko ni ojukanna pẹlu lojoujmọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu), pupọ ẹlomiran ẹwẹ nipa jijẹ Ṣuga tabi oniruru ohun adidun pupọju nigbakugba. Jẹdijẹdi orişirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ ade ninu omusu, tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnse, tabi ti o ba nyọ ti o ba ṣe igbẹnṣẹ tan ni, tabi ti arin ọ ninu omusu ni eyikeyi ti o ba ra bere egbogi "CYCLOVEN" ti awọn Oyinbo Jamani ṣeṣẹ wa idi rẹ io si panwo orişi mẹta ni o daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijedi katapata alafia yio de si ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata pboro Naijiria jakejado. Bere rẹ ni:

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Oja Ita Faji

## Awọn Ọn Ẹgbẹ Alakukọ Nse Ipade Lati Pari Ija To Wa Larin Awọn Ọmọ Ẹgbẹ

EKO:- Awọn agba ẹgbẹ Alakukọ (NCNC) si nṣe ipade lati pari ija to wa larin awọn ọmọ ẹgbẹ na ti Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Ipade na yio si bẹrẹ ni ọjọ' ru ti iṣe ọjọ kẹtala oṣu yi irohin lati ẹnu awọn ọmọ na fi ye wape Ọgbẹni T. O. S. Benson ti o jẹ igbakeji olori ẹgbẹ na ati Oloye Oju Akinfoṣilẹ ti o jẹ alaga na ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ati pe awọn meji yi ni o si jẹ Ogbokangi ti nwọn yio pari ija na fun, yio lọ sibi ipade na.

Ipade yi ni yio jẹ ipade ikẹjọ ti awọn alagba ẹgbẹ na yio pe ti o fi jẹ pe gbogbo ipade meje ti awọn alagba ẹgbẹ na ti pe sẹhin ti awọn mejeji ko si wa sibi ipade na rara.

AWỌN ALAGA

Ninu eyi ti yio jẹ ipade ẹkẹfa ti awọn alagba yio pe, ni Irohin fi ye wa pe Ọgbẹni Benson ti sọ fun awọn alagba pe ti awọn to nfi ẹsun kan on ba le fi oju kan oju ati pe ki nwọn si gbojugboya lati wa fi ìru ẹsun bẹ kan on.

Ọgbẹni Benson si sọ pe to ba jẹ pe awọn ẹgbẹ na fẹ yọ on kuro ni ẹgbẹ pe kii iṣe on nikan ni nwọn yo yọ ati pe to ba jẹpe ki on fi egbe na sile pe ki iṣe on nikan ni yio fi sile pe ọpọlọpọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ni yio fi silẹ.

Irohin tun fi ye wa pe ti awọn alagba ko ba gbinyanju lati pari ija na, yio si ba nkan jẹ fun awọn ọmọ ẹgbẹ na Ipinle Iwọ Orun.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Iwọ pẹlu obinrin kan yio gbadun ara nyin ninu awọn ti o ti mba yan odi fun iwọn ọse kan sẹhin, igbadun na yio miliyọ.

PISCES (Feb 21 – Mar 20) Iwọ lo ṣe ara rẹ nipa ifẹ lati jadun aiye, bẹni iwọ yio si ma jẹ adun na lọ fun iwọn ọsẹ kan.

ARIES (Mar 21 - April 20) Jẹ ẹniti o duro ṣinṣin ki o si ni otitọ, Bi o tilẹ jẹ wipe awọn to wa yi ọka ko mọ iru enia ti o jẹ, ni iforiti, otitọ, ati ododo.

TAURUS (April 21 – May 20) Pẹsẹ ni ọjọ oni yio jẹ fun ọ, ranti ki o maṣe lo o ni ilokulo nitoripe rere ni iro na ti a fun ọ.

GEMINI (May 21 – June 21) Awọn ẹbi rẹ yio fẹ lati ṣe atojubọ si nkan ti o nṣe, nwọn o si ma wa ọna lati ba alamọri rẹ jẹ.

CANCER (June 22 - July 23) Gbidanwo lati kapa ibinu rẹ, enia rẹ kan yio ṣe amodi ti amodi na yio damu rẹ pupọ, ṣugbọn ohun ti o mba ọ lẹru yio folọ.

LEO (July 23 – Aug 22) Idunnu ati ayọ yio wa fun ọ nigbati ilẹ ba su loni, mura fun igbaladun ayọ ju bi o ti lero lọ.

VIRGO (Aug. 23-Sept. 23) Ohun ayọ yio wọle tọ ọ, bofẹ bi o nwa a tabi o ko wa gbogbo nkan ti ti o ti nwa ni yio tẹ ọ lọwọ, yio si jẹ ajẹmọnu ati ajẹrire.

LIBRA Sept. (24 Oct 23) Iwọ yio bori iṣoro gbogbo ni opin ọsẹ yi ohun ayọ yio si joko ti ọ, ni gbogbo wahala ti o ti nṣe lori iṣẹ kan, nwọn o san owo atẹhinwa fun ọ, nwọn o si yin ọ logo.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) Sababi iwa jẹje ti o nhu, ina arisiki rẹ yio ma jo geregere. Ṣugbọn maṣe yọ ayọ ayọpọrọ depo ti iwọ yio fi gbagbe ara rẹ

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec. 22) Maṣe rin irin ajo loni, nitori oni ko dara fun irin ajo, maṣe jẹki edi mu ọ lati bọ sori irin ajo, maṣe lo nkan titun, masi ṣe lọwọ le iṣẹ titun.

CAPRICORN (Dec 23-Jan. 21) Irẹwẹsi ni gbogbo ọjọ oni jẹ fun ọ ọrẹ korikosun rẹ kan yio fẹ lati ba fọse rẹ jẹ, bi o si gbalaye lati ṣe bẹ yio ba bogbo nkan rere ti o ti ngbero jẹ ṣọra, ṣọra, ṣọra.'


## Congreves Remedy

(FUN OBINRIN)

Ojulowo egbogi titun fun gbogbo awọn Obinrin toba ni iyọnu tabi amodi Inu rirun nigbakugba tsa ni ẹkọọkan ẹhin-didun, ibadi-wiwo tabi sisan ẹjẹdudi ara tabi aikoto ẹj: lara Inu gbigbona nigbakugbi Igba — aiya riru ọmu riro, didun ara atinu wa ni o ma nfa oyi-oju Ilaogun ara ẹsẹ ara sisọn, ẹfori tabi pẹlu iba ati otutu Egbogi yi dara pupọ julọ fun itọju gbogbo Obinrin gẹgẹbi Ajo fun ilera ati oriṣiriṣi amodi miran ti o ma nyọ wọn lẹnu ni inu igbakugba pẹlu.

(OLOMI IGO NLA NI)

BERE EGBOGI ATI IỌ TI WỌN NPE NI:-

## Ammoniated Quinine Tincture

Nigba lailai ki awọn Oriṣiriṣi rọbirọbi egbogi ti wọn ko wa risisiyi to de awọn agbalagba aiye atijọ mọ daju wipe kosi ohun ti a le fi Iwe egbogi yi bi otutu ikọ iba, orẹrẹ lukuluku onigbameji tabi a i p e r i nyọ enia lẹnu yala Ọmọde tabi agbalagba ni yio ṣe iwosan rẹ bi danga ni bi oba ti ta diẹ sinu omi ti o lọwọrọ ki o si gbemu bere egbogi ti o daju fun itọju eti riro tabi didun, ati Akokoro, egbogi ti o ma nfọ apo-ile-itọ tabi se iwosan iyọnu apo-ile-itọ egbogi oju didun tabi ti ọna-ọfun didun, ati oriṣiriṣi omirau pẹlu wọn mbẹ ni ṣọbu awọn :—

Waterloo Medicine Stores,
8, PalmChurch Street, Lagos.
Phone:- 2287 Nigeria, (Oja Ita Faji)

ADEDUN CHEMIST
14. Wakeman Street Lagos

NIGERIAN MEDICINE STORE
Tinubu Square Lagos.



## Iyipada Ile Isẹ

Eyi nilati kede fun awọn Onibara wa pe ati ko ile itaja wa kuro ni Ibadan patapata asi ti wa si Ilu Itirẹ ni Agbegbe Suru Lere ati Mushin.

Ẹnikẹni ti o ba fẹ bawa ra Iwe tabi Turari Ajẹbidan Er o wa si ile itaja wa ni Nọmba 1, Ishiba Street Odo kan Itirẹ

## Apejuwe Ile Isẹ Wa

Ẹ wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ti oba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja rẹ Adirẹsi mi niyi:-

Shoyinka
c/o Postal Agent,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba


## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye
### Yoruba Debate

Ẹgbẹ Ariyanjiyan (Debate Club) ti Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye yio ṣe ariyanjiyan lori ọrọ kan eyiti ẹ o gbọ ki o to di ọjọ na ni ọjọ Sunday ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn oṣu yi ni deede agogo meji ọsan (31/5/64).

Nitorina a pe gbogbo enia lati wa wo ere na, A tete de ṣe pataki.

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

# Ọtẹlẹmuyẹ Nki Nyin O

Gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ ni mo ki nko ni olodi kan, mo tun ki Olotu paapa pe, "KUANA LAFIA MEGIDA" Ẹnyin aṣaṣo lohin Imọlẹ mo juba yin o; ẹ ku iṣẹ o asun gbagbe ko ni ba yin lagbara Edumare ati emi na o.

Nko gbọdọ ro ile apakan, lori idọbalẹ ni mo wa ti mo fi nki oludasilẹ iwe irohin na pe, ẹ ku iṣẹ o.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ ti jade, heya! ilẹ mọ. Ijapa ni ti a ba ṣọrọ titi ki a maṣe gbagbe ọrọ asọti ana, ibiti mo ba ọrọ mi de ni igbati mo lọ si ọdọ Woli eke na. Ohun ti o mu mi maa pe ni Woli eke ni mo fẹ ki ẹnyin Onkawe mi mọ iyatọ larin ati awọn Woli Ọlọrun ni.

ILẸ AANU

Nigbati mo de ibẹ mo ba a ti o tan ẹgbaagbeje abẹla si ilẹ aanu na kan, awọn obinrin si pọ lọ sura bi ewe sumọ ọkunrin arugbo kanṣoṣo ni mo ba pade nibẹ, olukuluku wọn si bẹrẹ si yi goiri nilẹ aanu, nwọn njẹwọ ẹṣẹ wọn Bi ọgan ni ẹmi paapa ti gbera wọnle bi oniwarada, mo si bẹrẹsi yi ni ilẹ, eyiti o wa buru niru ọrọ temi nipe mo farabọ yannayanna. Adura ni mo ti mo pe mo lọ gba ile dokita ni mo ro si ni ọjọ keji. Nigbati Dokita di gbogbo egbo ara mi tan, mo wa da bi "LASARU ELEGBO" Sibẹsibẹ nko dekun lati maa lọ jọsin pẹlu Woli Eke na titi mo fi ridi iwa jamba rẹ pata.

Ko to ọjọ, ko to oṣu ni o ba sọ mi di ariran agba.

O wa pe mi ni ọjọ kaa O sọ fun mi bayi pe, Lotitọ o ti di ariran nisisiyi, aiye ko fẹ otitọ, itori Ọlọrun ko si ni Mẹkka, juuju ni afi mbo ara wa loju nipa ti ọrọ Ọlọruu yi, Woli ti ko ba wo ọrọ owo mọ ọrọ tirẹ yio talẹka ju ekute ṣọọṣi, obinrin arẹwa wa nihin jaburata ti nwọn lojumeji. Arowoto awọn Woli ni gbowọn wa nitorina oti dele igbadun ati idẹra ti o ba ma jẹ, iwọ yio jẹ pẹ o"

Mo dupẹ lọwọ rẹ, mo si sọ fun ẹ e, Oluwa naa si wa lẹna. O ni amin o Ni kukuru a mba ere aniyan bọ, titi ọrọ fi wọ ara won.

Ẹnyin onkawe irohin Imọlẹ mo fẹ sọ fun yin pe laiṣe aniani ẹrun apadi ni awọn Woli eke nlọ nitoripe awọn ti lodi si ilana Oluwa.

Iwakiwa ti Woli Eke Na Nhu

Ekini nibẹrẹ lori ọrọ awọn obinrin ṣe ẹmọ pe ki iṣe ọjubọrọ ni enia fi nde ọdọ Woli ati Babalawo, yala idamu ajẹ ati airọmọbi ni o de ibẹ.

de ibẹ. Obinrin ti o ba ti de ọdọ Woli ti mo nwi yi wo gau. Bi ọkọ ba sọrọ, ko ni gbọ t'ọkọ a fi ti Woli. Bi Woli Eke yi ni ko gbọdọ ṣu ko gbọdọ, ko ni rẹkọja ofu ṣe. Igbakigba ti o ba wiwu ni o mba wọn lọ, pọ bi o ti lẹ

Ẹyiti o ba seeṣi loyun ninu awọn ti o ba ba sun, ọkọ rẹ tun da oran ni yen nitoripe yio gba pali abẹla meji la fuafun, ayinun ati kuburu pọun mẹwa ṣile mẹwa, sisi mẹwa tọrọ mẹwa kọbọ mẹwa ati epinni mẹwa lọwọ se, lẹhinna ni yio tun palaṣẹ fun Ọkọ iyawo na pe, ki o ṣe "ipese" rẹpẹtẹ wa si ṣọọṣi.

Ẹnyin onkawe mi, ohun ti oju awọn obinrin ti o nlọ silẹ aabo awọn Woli eke nri, ko ṣe de ile rohin.

ẸNITI O NWA IYAWO

Woli ti mo nwi yi. nwa iyawo fun enia larin ijọ rẹ ti o ba ti ni pọnun meji abọ "Owo bamiṣe."

Ti owo 'Bamise" na ba ti te Woli na lọwọ, bi ọgan ni yio ti rii loju iran pe, obinrin kan ninu ijọ re ati ọkunrin ti o ti gbowo "bamiṣe" lọwọ rẹ ni Oluwa sọ pọ atipe bi obinrin na ko ba fẹẹ, kiku ni yio ku, nigbati obinrin na ba si gbọ bẹẹ, aiya rẹ aja pẹẹ ni yio ja ọkọ rẹ ti o mu lọ si ṣọọsi silẹ, a si dirọ mọ ẹniti Woli eke na ni ki o fẹ. Ẹnyin onkawe mi bayi ni Woli eke na ṣe ile ti o ndun yungba di aboro.

Gbogbo bi o ti rpẹ mi si ilana buburu yi ni mo ngmu ori mu, nigbati o fura si mi pe ngo tuna asiri on nio ba sọ fun mi pe ki ngma wa jọsin ni ṣọọsi on mọ nitoripe Oluwa ni o wi bẹ ẹ fun oo.

Emi ti ti mo ti fẹ fi ṣọọṣi rẹ silẹ tẹletẹlẹ, nko bere ohun ti o faa ti o fi ni ki ngma wa si ṣọọṣi rẹ mọ, bi ọgan ni mo fi kuro nibẹ nigbati mo ri idi ohun ti wa tan.

"Ẹla lọrọ bi obinrin ba berẹ ala aṣọ bo idi" toto o ṣebi owe Woli eke ni mo nba wi o ki, kii iṣe ti Ọlọrun o Ọrọ mi yi dabi arandun, ṣugbọn ohun ti osẹlẹ gan an, eyi ni yio si ṣe amọna yin lati le ma jẹki awọn obinrin yin maa lọ jọsin lọdọ awọn Woli eke, nitoripe igbẹhin rẹ kii dara.

Emi Ọtẹlẹmuyẹ nrọ pe, inu awọn Woli eke ko ni dun si aṣeri wọn ti mo ntu yi, ẹru ko ba nu lati sọ Ododo nitoripe Olotitọ ko ni ku si ipo ika lailai, Laipẹ ẹ o tun maa gbọ bi o ti se ngba abẹla, aṣọ ati ewure bi Babalawo. O digba kanna o, ka fi ire pade o.

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI

ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki awọn Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ agbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo



Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala tabi ṣiṣe ti o ko le jẹun daradara, tabi ki o male sun daa la ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradarawọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti c nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ s'i dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugbd'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu. Igba-dun ati alafia yio de si ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbuṣa

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street, Lago-

BI O BA NI
Iwe—Titẹ
FUN
Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku
ATI
Iwe gbeyawo
TETE KỌWESI ILE—IṢẸ—ẸRỌ ITẸWE
Modupẹ Printing Press
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
OWO PỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TO AFOJUBA
Dan a wo lẹẹanṣoṣo ki o ri iyatọ

# IROHIN IMOLE

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE. TẸNI GBOGBO LAWA

No. 704 TUESDAY MAY 26, 1964 (2D)


## Apẹlẹwọn Kan Tun Gba kun Ẹwọn Rẹ

IBADAN:– Gbogbo ile ẹjọ kekere kan ni Ibadan lo kuusọsọ ni kutukutu owurọ ana ọjọ Aje ti ise ọjọ kẹdọgbọn osu yi nigbati awọn ọlọpa mu Ọdaran apẹlẹwọn kan Ọlakunle Arẹmu, ẹni ọdun mejilelogun wa siwaju adajọ fun ẹsun ile fifọ ati Ole jija.

Ọlọpa ti o ba ọdaran na ṣẹjọ ṣe alaye fun ile ẹjọ pe, ni ọjọ kejidinlogun oṣu keji ọdun yi ni ọdaran na lọ fọ ile Iyaafin Mọriamo Ayinkẹ ni Ode Aje Street ti o siko gbogbo awọn ẹru ti iye owo rẹ jẹ poun marun abọ (£5 10/-) ninu ile na.

Ọlọpa na tun ṣe alaye pe ninu ọgba ẹwọn Abẹokuta ni awọn ti mu ọdaran na wa nisisiyi nitoripe o wa ni ẹwọn ọdun mẹta nitoripe o ti lọ fọ ile kan siwaju ti Iyaafin Ayinkẹ ti adajọ si fi si ẹwọn.

Nigbati ẹlẹwọn na rojọ, ti o si tun gba pe, on jẹbi ẹsun na, ni adajọ ba ṣe idajọ ẹwọn Ọdun mẹta miran fun un kun Ọdun mẹta ti o ti wa lọwọ ni Ọgba ẹwọn Abẹokuta.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn Ọlọpa ti mu pada lọ si Ọgba ẹwọn Abẹokuta, nibiti yio ti lọ ẹwọn Ọdun mẹfa,

# MỌTO—AKERO KAN KO SI ẸNU ỌKỌ RELUWE

## Enia Mọkanla Farapa; Ṣugbọn Ko Si Eniti O Ku Ninu Wọn

KAFANCHAN:— Gbogbo ilu gbojikan fun ariwo, idaamu nla si ba gbogbo enia nigbati mọto Akero kan mbọ lati Kagoro lọ si Gida Waya ti o si fẹ sare kọja ki Ọkọ reluwe ti mbọ o to de, ṣugbọn mọto na ati Ọkọ reluwe ni nwọn jijọ pade ti mọto na si fi ori sọ Ọkọ reluwe ni Ọjọ Ẹti iṣe Ọjọ kẹtalelogun Oṣu yi.

Lẹsẹkẹsẹ ni Ọkọ reluwe na yara tete duro, ṣugbọn ariwo ti awọn ara ilu gbọ ni gbogbo wọn ba sare fi iṣẹ ti nwọn nṣe silẹ ti nwọn si sare wa wo ohunti ti o ṣelẹ.

Nigbati nwọn de, ni nwọn ba ri mọto akero na, ti awọn enia ti o wa ninu mọto na nsunkun ti awọn miran si nkigbe," Ori mi , Oju mi o, ẹhin mi o, ibaradi mi ti yẹ o, apa mi ti da o, egungun ẹhin mi ti ge o, kini mo kan loni yi o?"

Lojukanna ni awọn enia na ba sare wọ inu mọto na ti wọn si ṣi ilẹkun, ti nwọn ngbe awọn ero inu mọto na sọkalẹ ni Ọkọọkan nitoripe awọn ero inu Ọkọ na ti fi ara pa pupọ ti o fi jẹ wipe ko si ẹniti o le sokalẹ furarẹ ninu wọn.

Nigbati nwọn gbe awọn ero inu mọto na sọkalẹ tan ni nwọn wa ripe, ko si ẹniti ko fi arapa ninu wọn enia mọkanla ni ofi arapa ju ṣugbọn ti awọn enia marun lo pọju ninu wọn ti awọn yoku wọn ko to nkan.

Lẹsẹkẹsẹ ni nwọn ko gbogbo wọn lọ si ile iwosan, lati lọ ṣe itọju wọn ṣugbọn awọn marun ti aye ti nwọn wa lẹlẹgẹ na nwọ daduro, nwọn ni ki awọn yoku maa lọ si ile ṣugbọn ki nwọn maa wa ni ojojumọ lati maa wa wẹ oju ọgbẹ wọn ki wọn situn maa gba abẹrẹ pelu.

Irohin awọn ọlọpa asọmọto ilu Kafanchan fi ye wa pe mọto akero na rekọja atunṣe, ṣugbọn awa mọto na ko farapa awọn ọlọpa si ti mu awamọto na lati bere ọrọ lọwọ rẹ bi oti ṣe wa mọto kosi ẹnu ọkọ reluwe.

Bi nwọn bati nsọ ọrọ na si ẹ̀ tun ma gbọ. Ki Ọlọrun fun awọn ero inu mọto na ni alafia o.

Oniwe irohin na tun fi ye wa pe ni ana ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu yi ni Ọsẹ meji ti Minista na ṣe ileri ti pe, awọn ko si ti tun gbọ nkankan.


AT LAST THE WATCH WITH A PERSONAL TOUCH WITH YOUR PHOTO REPRODUCED ON THE DIAL

A fortnight after receipt of your photo we will send you a Windsor watch with lifetime guarantee

REf. N° 55. PHOTO

Free illustrated catalogue on demand



A Wonderful 15 Jewel lever shock protected movement, non-magnetic, unbreakable mainspring ROLLED GOLD waterproof case and stainless steel back with your name engraved. Beautiful diamond polish raised figures, luminous and YOUR PHOTO reproduced IN COLOR on metal dial.

PRICE £ 5.

HURRY SEND YOUR PHOTO (any size) with cash or cheque

WINDSOR

19, Avenue de Lérins – Cannes, France


# Afikun Owo Oṣu Ọṣiṣẹ

## Lati oju ewe kini

Lati Ọjọ ti Minista na ti se ileri ni gbogbo awọn Asiwaju ẹgbẹ Oṣelu ni Eko ati Ipinlẹ ti ngbe Oju soke bi akọpẹ, ti nwọn si tẹti leko ti nwọn nreti abayọri iwadi na, ṣugbọn titi ti Ọsẹ meji na fi pe ni alẹ ana ofo ni gbogbo ireti awọn na jasi fun awọn.

OFIN PAJAWIRI

Ọkan ninu awọn Asiwaju ẹgbẹ Oṣelu fi ye Oniwe irohin wa lana pe, ti Apapọ Ijọba Naijiria ko ba gbe abayọri iwadi ẹkunwo Oṣu awọn Oṣiṣẹ na jade loni, gbogbo awọn Oṣiṣẹ jakejado Orilẹ-ede yi ni yio da iṣẹ silẹ ni Owurọ yi.

Asiwaju ẹgbẹ awọn ọṣiṣẹ na tun ṣe afikun ninu alaye rẹ pe ki iṣe ni igboro ilu Eko nikan ni awọn osiṣẹ yio da iṣe silẹ loni, ti Apapọ Ijọba bą fi le kuna lati gba abayọri eto Igbimọ Oluwadi na jade ṣugbọn jakejado orilẹ-ede yi ni pelu

Asiwaju ẹgbẹ awọn osiṣẹ na tun se alaye fun oniwe irohin wa pe, gbogbo awọn osiṣẹ ni nwọn o lọ si ibi iṣe ṣugbọn nwọn yio joko kalẹ laiko fi ọwọ kan ohunkohun ṣe.

Gbogbo awọn Asiwaju ẹgbẹ oṣelu na ni nwọn ṣe ipade bonkẹlẹ kan ni alẹ ana lati fi mọ ohun ti awọn yio ṣe ni owurọ yi bi Apapọ Ijọba ba kuna lati gbe abayọri ẹkunwo owo oṣu awọn osiṣẹ na jade loni.

Lẹhinti nwọn pari ipade na ni oru ana, ni gbogbo wọn wa pinnu lati duro de ohunti Ọgbẹni J. C. Ọbande fẹ sọ ni owurọ yi, nwọn tun ṣe alaye lori ọrọ ti o ba sọ ni nwọn yio ṣe loni, bi awọn yio da iṣọ silẹ tabi awọn yio maa ba iṣẹ lọ.

Ni ipari ipade ti nwọn ṣe ni alẹ ana, awọn enia na kọ lati fi ori ọrọ wọn ti lori ipinnu gbẹdogi kan, nwọn sipẹ fun ara wọn lati mu suru di owurọ yi lati gbọ kini Ọgbẹni J. C. Oban de fẹ ba wọn sọ.

Ṣugbọn oniwe irohin wa kan ti o mọ ero ọkan awọn oṣiṣẹ fi ye wa pe, ẹhun ti gbogbo awọn oṣiṣẹ nreti ni sisiyi bi oṣu Aawẹ ni abayọri iwadi ẹkunwo owo eṣu ti Ijọba fẹ gba jade.

Onirohin wa na, ni bi oran ti ṣe ndun awọn asiwaju ẹgbẹ oṣiṣẹ, bẹẹni o ndun awọn ọṣiṣẹ kọọkan lọkan, ti elomiran ko ro nkan meji lọkan ju ẹkunwo owo oṣu na lọ.

Bi nwọn ba ti pari ọrọ na si ni owurọ yi, ẹ o ma a gbọ ninu iwe irohin wa ni owurọ ọla.


Printed and Published by Modupẹ Printing Press 16, Baugbose Street Lagos Phone 21985
Editor;- TUNJI ADEOSUN 45, Campbell Street, Lagos 26/5/64